# Kíkọ́ Àjòjì Ní Gírámà Èdè Yorùbá: Àkóónú Àti Ọgbọ́n-Ìkọni

Harrison Adéníyì
Lagos State University, Nigeria
harrison.adeniyi@lasu.edu.ng

## Àsamọ̀

Ó pọn dandan láti wá ọ̀nà tí àwọn àjọ̀jì tí wọ́n nífẹ̀ẹ́ láti kọ́ àti láti mọ̀ èdè Yorùbá yóò gbà tí yóò fi rọ̀ wọ́n lọ́rùn lái sí pé kíkọ́ èdè Yorùbá ń kọ wọ́n lóminú. Ìdí pàtàkì ni pé ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ nínú àwọn tí ó fẹ́ kọ́ èdè yìí ni ó jẹ́ wí pé kì í ṣe fún sísọ nìkan tàbí kíkọ́ léréfèé, bíkọ̀ṣe pé wọ́n fẹ́ ní ìmọ̀ tí ó kún tí àwọn náà yóò fi lè ṣè bí ọmọ bíbí Yorùbá. Ẹ̀kọ gbígbóná ni ọ̀rọ̀ kíkọ́ gírámà èdè jẹ́, ó ń fẹ́ sùúrù gidigidi. Nítorí ìdí èyí, àwa Olùkọ́ èdè Yorùbá ní láti wá ọ̀nà tí yóò jẹ́ kí kíkọ́ àti mímọ̀ èdè Yorùbá àti pàápàá gírámà èdè, dàbí pé à ń fi ẹran jẹ̀kọ. Ohun ti yóò jẹ wá lógún jù nínú isẹ́ yìí ni pé a ó wo bí a ṣe lè kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí, tí wọ́n tún jẹ́ àjòjì, ní gírámà èdè Yorùbá lái sí pé a lè wọn sá láti kọ́ àti láti mọ èdè yìí. A ó wo gbogbo àwọn ohun tí ó yẹ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ nínú gírámà èdè Yorùbá, àwọn ìpele tí ó yẹ kí wọ́n ti mọ̀ ón àti bí ó ti yẹ kí á kọ́ wọn ní ìpele kọ̀ọ̀kan. A ó bèèrè, a ó sì tún dáhùn ìdí tí àwọn àjòjì fi níféẹ́ láti kọ́ àti láti mọ èdè Yorùbá. Gbogbo ohun tí ó yẹ kí ó wà nínú àkọ̀ónú tí akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ mọ̀ ni a ọ̀ yẹ̀ wọ̀ fínnífínní. Lẹ́yìn èyí, a ó tún wo gbogbo ọgbọ́n ìkọni tí a lè lò tí yóò fi jẹ́ kí kíkọ́ gírámà èdè rọrùn fún wa láti kọ́, kí ó sì tún rọrùn fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti mọ̀. Lẹ́yìn èyi, a ó sọ̀rọ̀ lẹ́kùn-uń rẹ́rẹ́ lórí bí ó ṣe yẹ kí á kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí ní àkọ́dunnú tí yóò fi jẹ́ kí èdè Yorùbá wù wọ́n lọ́pọ̀lọpọ̀.

## Ìfáárà

Ńinú gbogbo abala ẹ̀kọ́ èdè, gírámà ni a lérò pé ó ṣòro díẹ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti kọ́ àti láti mọ̀ jù. Yálà fún akẹ́kọ̀ọ́ tí ó fẹ́ kọ́ èdè gẹ́gẹ́ bí èdè àbínibí ni tàbí èyí tí ó ń kọ́ ọ gẹ́gẹ́ bí i èdè àkọ́kúntẹni. Ó tilẹ̀ ma ń ṣòro ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà tí ó fi jẹ́ pé ọ̀pọ̀ nínú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èdè àbínibí yìí ni ó ma ń fi gìrámà ṣe àgbérù-àgbẹ́sọ̀ tí o fi jẹ́ pé tí wọ́n bá ti parí ìdánwo lori ẹ̀kọ́ èdè, wọ́n lè má rántí ohun

tí wọ́n kọ́ wọn lórí rẹ̀ mọ́. Nítorí náà, olùkọ́kólùkọ́, tí ó bá fẹ́ kọ́ àwọn ọmọ ní gírámà èdè gbọ́dọ̀ lè farabalẹ̀ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè máa fi ọkàn bá ohun tí olùkọ́ ń kọ́ wọn kí iṣẹ́ àwọn olùkọ́ yìí lè kẹ́ṣe járí. Ohun tí ó ṣe pàtàkì nínú kíkọ́ gírámà èdè lápapọ̀ ni pé àwọn ìlànà kán wà gbógì tí a ti lapa tí gbogbo àwa tí à ń kọ́ èdè àjòjì yìí ti fọwọ́ sí láti máa fi kọ́ àwọn ọmọ ní èdè yìí.

Gbogbo àwọn olùkọ́ tí ó bá fẹ́ kọ́ gírámà èdè, pàápàá, èdè àjòjì, gbọ́dọ̀ ti ní ìmọ̀ tó kún gidi lóri ìlànà yìí tí ó fi jẹ́ pé a kọ̀ ní i ma sọ kába kàba nígbà tí a bá dé iwájú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí. Ohun tí a fẹ́ kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí yóò ti di bár-akú fún wa, kí àwa olùkọ̀ọ́ pàápàá sì ti mọ̀ ọ́n ní àmọ̀dunjú. Tí èyí bá ti wá ri bẹ́ẹ̀, ohun tí ó kù tí àwa gbọ́dọ̀ ṣe ni bí a ó ṣe kọ́ àwọn ọmọ náà ní àkọ́dunnú tí inú wọn yóò fi dùn tí èrèdí tí wọ́n fi fẹ́ kọ́ èdè Yorùbá yìí kọ̀ fi ní í já sásán, tí wọn yóò sì fi gbádùn ohun tí àwa olùkọ́ ń kọ́ wọn.

Ohun mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì tí a gbọ́dọ̀ fiyèsí ni pé à ń kọ́ Yorùbá fún àwọn àjòjì yìí gẹ́gẹ́ bí èdè àkọ́kúntẹni ni, àṣà wọn yàtọ̀ gédégédé sí ti Yorùbá. A ò gbọdọ̀ ni lọ́kàn pé wọn kò mọ ohunkóhun nínú àṣà tàbí ìṣe wa. Tí a bá ti ń kọ́ wọn, ohun tí ó bá jọra nínú àṣà wa pẹ̀lú tiwọn, a ó jẹ́ kí wón tètè mọ̀, nítorí ìmọ̀ fi yẹ́ wa pé àwọn tí ó ń kọ́ èdè àkọ́kúntẹni má ń tètè fọkàn bá ohun tí wọ́n bá ń kọ́ wọn nínú èdè yìí lọ tí ó bá jọra pẹ̀lú tiwọn. Àpẹẹrẹ tí a lè tọ́ka sí ni ìwádìí tí Oyètádé (2004) tí ó sọ pé bátànì sílébù èdè Yorùbá àti ti àwọn ará Jàpánì jọra gan an ni. A sì tún gbọ́dọ̀ tẹmpẹlẹ mọ́ àwọn ohun tí kò jọra rárá nínú àwọn èdè yìí.

## Ìdí tí àwọn àjòjì fi ní ìfẹ́ sí kíkọ́ èdè Yorùbá

Ọ̀pọ̀ ìwádìí ni ó ti wà lórí àwọn ìdí tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ fi nífẹ̀ẹ́ sí kíkọ́ èdè Yorùbá, àti pàápàá àwọn èdè ilẹ̀ Afíríkà. (Àrásanyìn, Schleicher àti Ṣekóoní 1996). A ní láti bèèrè lọ́wọ́ ara wa pé kí tiẹ̀ ni àwọn àjòjì yìí rí lọ́bẹ̀ tí wọ́n fi waro ọwọ́. Kí ni wọ́n rí nínú àṣà àti èdè Yorùbá tí wọ́n fi nífẹ̀ẹ́ láti kọ́ ọ. Kí ni wọ́n rí nínú èdè Yorùbá tí ó wú wọ́n lórí tí àwọn ìjoba òkèèrè sì fi ń ná ẹg-bẹ̀rún lọ́nà ẹgbẹẹgbẹ̀rún mílíọ̀nù dọ́là sórí èdè àti àṣà Yorùbá, tí àwọn ọmọ wọn náà sì fi ń rúnpá-rúnsè sí kíkọ́ èdè yìí. Tí a bá wòó, lọ́wọ́lọ́wọ́ báyìí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ orílẹ̀-èdè àgbáyé ni àwọn àjòjì ti ń kọ́ èdè àti àṣà Yorùbá ní ilẹ́-ẹ̀kọ́ Yunífásítì wọn, ní àwọn orílè-èdè bí i Jàpáàǹì, Jámánì, Faransẹ́, Kúbà, Gẹ̀ẹ́sì, Brasili àti àgàgà ilẹ̀ Amẹ́ríkà.

Ohun tí a gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ mọ̀ ni pẹ́ tí àwọn orílẹ̀-èdè yìí kọ̀ bá fi ààyè gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tàbí kí wọ́n fún wọn ní ìwúrí tí ó yẹ, ó lè ṣòro díẹ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tàbí olùkọ́ tí ó fẹ́ kọ́ èdè Yorùbá yìí. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, Nínú ìwé òfin òkèèrè ilẹ̀ Amẹ́ríkà, wọ́n fi ààyè gba àwọn ọmọ ilẹ̀ Amẹ́ríkà láti kọ́ èdè ilẹ̀ òkèèrè nítorí àwọn ìdí mẹ́ta tí ó so mọ́ ara wọn. Àwọn ìdí náà nìwọ̀nyìí gẹ́gẹ́ bí Adéníyì (2005:247) ti sọ:

a. U.S Army's interests in developing a national capacity or manpower in five key areas; mathematics, physics, electicity, engineering, and foreing languages during World War 11.
b. U.S perceived need for international education with particular refence to the study of foreign languages and cultures; and
c. Colleges and universities' continued intellectual pursuits. [Lambert 1984; 1994a; Dougherty 1993, Ruther 1994; Kantz 1996, Swenson 1999, Kurtt 1999, and Hare 1999].

Yàtọ̀ sí ìdí tí a mẹ́nubà lókè yìí, ọ̀pọ̀ ìdí ni a tún lérò pé ó ń jẹ́ kí àwọn àjòjì nífẹ̀ẹ́ láti kọ́ èdè Yorùbá. A rí lára àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí tí ó jẹ́ pé dúdú ni wọn tí wọ́n sì ní ìgbàgbọ́ pé ilẹ̀ Áfíríkà àti pàápàá, ilẹ̀ Yorùbá ni àwọn ti sẹ̀ wá, tí wọ́n ti kó àwọn baba ńlá bàbá àwọn lẹ́rú lọ sí orílẹ̀-èdè bíi Amẹ́ríkà, Kúbà, Brasili, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nítorí náà, wọ́n ma ń fẹ́ láti kọ́ èdè àti àṣà Yorùbá kí wọ́n lè mọ̀ ibi tí wọ́n ti sẹ̀ wá kí wọ́n sì tún lè mọ kúlẹ̀kúlẹ̀ èdè yìí. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn tilẹ̀ wà tí ó jẹ́ ìfẹ́ àti mọ èdè àjèji nìkan ni ó jẹ wọ́n lógún, tí ó fi jẹ́ pé wọ́n ma ń rúnpá-rúnsẹ̀ sí kíkọ́ èdè àti àṣà Yorùbá. A tún tilẹ̀ rí lára àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí tí wọ́n lérò pé lọ́jọ́ iwájú, àwọn yóó rin ìrìn-àjò wá sí ilẹ̀ Yorùbá, tàbí kí wọ́n tẹ̀dó tàbí sisẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn mìíràn tilẹ̀ lè fẹ́ ṣe àkànṣe isẹ́ ìwádìí. Nítorí ìdí èyí, wọ́n ma ń mú kíkọ́ èdè àti àṣà Yorùbá ní ọ̀kúnkúndùn.

Yàtọ̀ sí àwọn ìdí tí a mẹ́nubà lókè yìí, a tún rí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn tí wọ́n nífẹ̀ẹ́ láti kọ́ èdè àti àṣà Yorùbá nítorí pé wọ́n fẹ́ràn àṣà àti òrìṣà ilẹ̀ òkèèrè. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí ni wọ́n nífẹ̀ẹ́ sí àwọn àṣà àti ọ̀rìṣà ilẹ̀ Yorùbá bíi Ṣàngó, Ọya, Ọ̀ṣun, Ọbàtálá, Ifá, Ọ̀rúnmìlà, àti àwọn àṣà bíi irun dídì, ìkómọ-jáde, òkú ṣíṣe àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ó bá sì wàá rí báyìí, Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ẹni tí ń wá orí ahun tí ó tún ń wá ẹsẹ̀ ahun, odidi ahun ni yóò rà. Kò sí bí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí yóò ṣe kọ́ nípa àwọn òrìṣà àti àṣà ilẹ̀ Yorùbá yìí tí wọn kò ní kọ́ èdè Yorùbá. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn tilẹ̀ tún wà tí ó jẹ́ pé wọ́n kàn fẹ́ kọ́ èdè yìí kí wọ́n lè jẹ àǹfààní ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ tí ó wà fún àwọn tí ó bá yan èdè-ilẹ̀ Afíríkà kan láàyò ni. Nítorí pé owó tabua ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìjọba orílẹ̀-èdè yìí ma ń gbé kalẹ̀ lọ́dọọdún fún àwọn àjèjì tí ó bá nífẹ̀ẹ́ tàbí yan àwọn èdè yìí láàyò.

Ó pọn dandan ní gbogbo àwọn ilé –ẹ̀kọ́ Yunifásítì ní ilẹ̀ òkèèrè àti pàápàá ilẹ̀ Amẹ́ríkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti kọ́ èdè àjèjì kan kí wọn tó lè yege nínú ẹ̀kọ́ àti gba oyè gíga wọn. Tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀, àwọn èdè àjèji tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí gbọ́dọ̀ ṣe ni àwọn èyi tí àwọn aláṣẹ Yunifásítì náà ti fọwọ́ sí bí àwọn èdè ilẹ̀ òkèèrè bí i Faransé, Potugí, Sípáánìṣì, Jámánì, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀ àwọn aláṣẹ ilé-ẹ̀kọ́ Yunifásítì yìí ni wọ́n ti gba èdè bí i Yorùbá, Swahili, àti Zulu wọlé gẹ́gẹ́ bí èdè tí akẹ́kọ̀ọ́ tún lè ṣe. Ọ̀pọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gboyè yìí ni ó sì yan èdè Yorùbá láàyò. Lákòótán, a má ń rí àwọn olùdámọ̀ràn àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí tí wọ́n ma ń gba akẹ́kọ̀ọ́ nímọ̀ràn tàbí níyànjú láti mú èdè Yorùbá nítorí ọ̀pọ̀ ohun tí ó wà nínú àwọn àṣà àti èdè Yorùbá tí a ti meńubà lókè yìí

## Àkóónú

Ìbéèrè tí a kọ́kọ́ gbọ́dọ̀ bi ara wa ni pé kí ni àwọn ohun tí ó yẹ kí á kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ nínú gírámà èdè Yorùbá. Ìdáhùn tí a sì lérò pé ó tọ̀nà gan an ni pé ìpele tí akẹ́kọ̀ọ́ bá wà ni yóò sọ ohun tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ mọ̀ tàbí ohun tí ó yẹ kí á kọ́ wọn. Ohun tí ó gbọ́dọ̀ dá wa lójú ni pé ìgbà tí akẹ́kọ̀ọ́ bá fi máa dé ìpele ìgòkè-àgbà (superior level), ìmọ̀ rẹ̀ nínú gírámà ti gbọ́dọ̀ kún tó ìmọ̀ elédè àbínibí. Kí ni akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ mọ̀ ní ìpele ìbẹ̀rẹ̀ (beginning), kí ni ó gbọ́dọ̀ mọ̀ tí ó bá ti dé ipele agbedeméjì (intermediate) kí sì ni ó yẹ kí ó ti mọ̀ tí ó bá ti dé ìpele gíga (advanced)? Ohun tí ó yẹ kí a ṣe ni pé kí á kó gbogbo ohun tí ó yẹ kí á kọ́ nínú gírámà dà sílẹ̀, kí á wá pín wọn sí ọ̀nà mẹ́rin tí ó fi jẹ́ pé ní ìpele kọ̀ọ̀kan, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ lè kún ojú ìwọ̀n nínú ìpele kan kí ó tó tẹ̀ síwájú sí ìpele mìíràn.

Bí a ṣe sọ síwájú, gbogbo ohun tí ó wà nínú gírámà èdè Yorùbá ni ọmọ gbọ́dọ̀ mọ̀ tí ó bá fi má a dé ìpele tí ó ga jù, ìyẹn ni ìpele ìgòkè-àgbà. Ọmọ tí ó fẹ́ kọ́ èdè Yorùbá gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa ọ̀rọ̀ orúkọ àti bí a ṣe ń ṣẹ̀dá wọn. Ọ̀rọ̀ arọ́pọ̀-orúkọ náà ṣe pàtàkì àti oríṣiríṣi àpólà-orúkọ tí ó wà. Lẹ́yìn èyí, a gbọ́dọ̀ lè kó ọmọ ní ọ̀rọ̀-ìṣe, àpólà-ìṣe, ọ̀rọ̀-ìṣe àsínpọ̀, àsìkò àti ìbá ìṣẹ̀lẹ̀, ọ̀rọ̀ àpọ́nlé ọ̀ǹkà Yorùbá, àpèjúwe àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lẹ́yìn èyi akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa oríṣiríṣi àpólà tí ó wà nínú gírámà èdè Yorùbá àti bí a ṣe ń ṣẹ̀dá wọn. Ní ìparí, a gbọ́dọ̀ jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ nípa oríṣiríṣi èyà gbólóhùn àti awẹ́ gbólóhùn tí a ní nínú èdè Yorùbá.

## Ọgbọ́n Ìkọ́ni

Ọ̀nà tí àwa lérò pé ó yáàyì jùlọ láti la ojú àjèjì sí ẹ̀kọ́ gírámà láì fa ìpayà fún wọn ni ọgbọ́n títí ibi pẹlẹbẹ mú ọ̀ọ̀lẹ̀ jẹ tàbí òye agbọ̀n híhun. Ohun tí a gbọ́dọ̀ mú lókùnkúnúndùn ni ìbéèrè pé 'kí ni ó sún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yii dé kíláàsì gan an?' Ìyẹn ni pé ohun tí ó ti àwọn ọmọ dé kíláàsì yìí yóò ràn wá lọ́wọ́ láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ fọkàn sí nǹkan tí ó wá kọ́. Èyí ni Folárin-Schleicher àti Móshì (2000) pè ní *goal-based approach* (GBA). Gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe sọ, wọ́n ní:

> [GBA] is an approach that systematically integrates students' needs, academic interests or research interests into language instruction centers language instruction on the needs and interests of students in the context of meaningful, functional and cooperative experiences in order to develop in students motivation and interest in learning process.

Ohun tì àyọkà òkè yìí ń fi yé wa ni pé ohun tí ó bá ń wu ọmọ jẹ ni ó yẹ kí ó run ọmọ nínú ni ó yẹ kí kíkọ́ gírámà èdè fún àjòjì jẹ́. Kò tọ súnà rárá kí a kàn lérò pé ohun tí ó bá wù wá tí a lérò lọ́kàn ara wa pé ó yẹ kí wọ́n mọ̀ ni a

gbọ́dọ̀ kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí. Tí a bá kọ́ wọn ní ohun tí wọ́n fẹ́ àti èyí tí ó wù wọ́n, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí yóò lè kọ́ gírámà èdè Yorùbá ní àkọ́dunjú, tí ìmọ̀ wọn yóò sì kún nínú èdè yìí. Folárin-Schleicher àti Moshi (2000) jẹ́ kí á mọ̀ pé kìí ṣe pé àwọn ní kí àwọn olùkọ́ má lo ìmọ̀-ajẹmọ́lílò (functional approach) tàbí ìmọ̀-ajẹmọ́síṣọ (communicative approach) mọ̀ nítorí pé àwọn ìmọ̀ yìí wúlò gidigidi, ṣùgbọ́n ó yẹ kí olùkọ́kólùkọ́ lè pa gbogbo àwọn ìmọ̀ yìí pọ̀, kí wọn di odidi kí ó lè jẹ́ kí àwọn àjòjì akẹ́kọ̀ọ́ yìí ní ìmọ̀ tí ó kún dé ojú ìwọ̀n ninu gírámà èdè lóri ohun tí wọ́n fẹ́ kọ́.

Tí a bá ti ẹ wo ohun tí a ko sókè lórí àwọn ìdí tí àwọn àjòjì fi ń kó èdè Yorùbá, a óò rí pé ọ̀pọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí tí ó bá mú lọ́kàn gidigidi ni kò ní ko ohun tí yóò ná won láti kọ́ èdè yìí, nítorí náà, àwa náà gbọ́dọ̀ lè lo aǹfàaní ohun ti wọ́n ní lọ́kàn láti mú lò kí kíkọ́ èdè Yorùbá lè rọ̀ wọ́n lọ́rùn.

Ohun mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì ni kíkọ́ ọmọ ni gírámà èdè Yorùbá ni pé ẹni tí ó bá fẹ́ dásọ fún 'ni, tí ọrùn ẹ̀ ni a gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ wò. Ìmọ̀ olùkọ́ gan an gbọ́dọ̀ kún, kí ó tiẹ̀ tún má a ṣàn sílẹ̀ lórí ohun tí ó fẹ́ kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Olùkọ́ gbọ́dọ̀ lè mọ̀ gbogbo àpadé àti àludé ohun tí ó wà nínú gírámà èdè Yorùbá. A mọ̀ pé irú wá ògìrì wá ni ọ̀pọ̀ nínú àwọn olùkọ́ tí a ní tí ó ń kọ́ èdè Yorùbá fún àwọn àjòjì ní ọ̀pọ̀ ilẹ̀ òkèèrè. Ọ̀pọ̀ nínú wọn ni ó jẹ́ pé wọn kò gba oyè lórí ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá tàbí kí wọ́n má tilẹ̀ ṣe é rárá mọ́ abala ẹ̀kọ́ wọn ní Yunifásítì. Lójú tiwa, èyí kì í ṣe àbùkù rárá. Nítorí pé wọ́n jẹ́ ọmọ bíbí Yorùbá, wọ́n sì níféẹ̀ àti kọ́ àwọn ọmọ, ohun tí ó kàn kù ni kí wón ṣe tán àti fi ìmọ̀ kún ìmọ̀ wọn lórí gírámà èdè Yorùbá, nítorí pé tí a bá bí ni, a tún gbọ́dọ̀ tún ara wa bí.

Àwa tilẹ̀ lérò pé àlékún ni èyí yóò jẹ́ nítorí pé irú àwọn olùkọ́ báylí yóò tún lè mú nínú ìmọ̀ tí wọn ti ní tẹ́lẹ̀ láti lè lò fún kíkọ́ èdè Yorùbá. A kọ̀ gbọ́dọ̀ lérò pé nítorí pé ó jẹ́ èdè Yorùbá tí à ń sọ, kí a fi ojú tẹ́ḿbẹ́lú rẹ̀ láti má fẹ́ láti wá ìmọ̀ kún ìmọ̀, sẹ́ a mọ̀ pé ohun tí ó wà lẹ́yìn ẹ̀fà ó ju èje lọ, ohun tí ó wà nínú kíkọ́ gírámà èdè Yorùbá ju kí a kàn kọ́ àwọn ọmọ yìí ní a, b, d, lọ, nítorí náà, olùkọ́ gbọ́dọ̀ má a ṣe ìwádìí tí ó jinlẹ̀ tí ó sì múná dóko lori gírámà èdè Yorùbá. Ó sì gbọ́dọ̀ lè ma mú àwọn ìmọ̀ yìí lò lóòrèkóòrè tí ó bá ti ń kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ohun tí ó tún ṣe pátàkì tí a gbọ́dọ̀ mẹ́nuba lábẹ́ ìsọ̀rí yìí ni òwe Yorùbá tí ó sọ pé ẹgbẹ́ ẹyẹ ni ẹyẹ ń wọ́ tọ̀.

Gbogbo àwọn olùkọ̀ èdè Yorùbá àti ti ilẹ̀ Afíríkà pàápàá ma ń pàdé lóòrèkóòrè lati fi ikùn lukùn lórí bi ìlọsíwájú yóò ṣe bá kíkọ́ àwọn àjèjì ní èdè ilẹ̀ Afíríkà lágbàáyé àti pàápàá ní orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà. Nínú ìpàdé yìí, wọ́n ma ń tú iṣu dé ìsàlẹ̀ ìkòkò lórí bí ìlọsíwájú yóò ṣe bá kíkọ́ àwọn àjèjì ní èdè ilẹ̀ Afíríkà. Aǹfàànì ńlánlà ni èyí máa ń jẹ́ fún àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá nítorí pẹ́ ọ̀pọ̀ ọgbọ́n kíkọ́ni ní gírámà èdè ni ó máa ń jáde láti ibẹ̀ tí àwọn èèyan ma ń kọ́, tí wọ́n sì ma ń múlò fún kíkọ́ èdè Yorùbá. Olùkọ́ èdè Yorùbá tí ó bá fẹ́ gbéwọ̀n ní kíkọ́ gírámà gbọ́dọ̀ fi sọ́kàn láti má ma pà ìpàdé yìí jẹ. Èkejì tí ó tún dàbí rẹ̀ ni ìpàdé àkànṣe-isẹ́ kan tí àjọ Natioanl African Language Resource

Center, University of Wisconsin, Madison má ń ṣe agbátẹrù ní ọdọọdún, èyí tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Antonia Folárìn-Schleicher ń ṣe alákoso rẹ̀.

Nínú ìpàdé àkànṣe-iṣẹ́ yìí ni wọ́n ti ma ń kọ́ àwọn olùkọ́ ní àkóónú àti ọgbọ́n ìkọni bí ó ṣe yẹ kí wọ́n má a kọ́ àwọn àjèjì ní gírámà èdè ilẹ̀ Afíríkà. Lára ìrírí wa ni a tún ti rí àwọn olùkọ́ tí wọ́n tilẹ̀ sọ pé àwọn ma ń kọ́kọ́ kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí ní gírámà èdè Yorùbá pẹ̀lú èdè gẹ̀ẹ́sì. Wọ́n ní àwọn á kọ́kọ́ fi èdè gẹ̀ẹ́sì kọ́ wọn kí àwọn tó wá ṣe ògbifọ̀ rè sí èdè Yorùbá, àwá lérò pé èyí kò tọ̀nà rárá. Tí a bá ti wọ inú kíláàsì ni a ti gbọ́dọ̀ jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí mọ inú odó tí wọn ń da ọ̀rá sí, kí wọn lè tètè mọ bí wọ́n yóò fi sọ́kàn gbogbo ìṣòro tí ó wà níwájú wọn àti bí wọn ṣe lè kojú rẹ̀. Tí a bá tún ń fi èdè gẹ̀ẹ́sì kọ́ gírámà èdè Yorùbá, a kò ní ran àwọn ọmọ yìí lọ́wọ́ rárá, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ní ìbẹ̀rẹ̀, inú wọn yóò máa dùn, ṣùgbọ́n lẹ́yìn ọ̀ reyìn àwọn ọmọ yìí kọ̀ ní kún ojú ìwọ̀n nínú iṣẹ́ wọn.

Kíkọ́ èdè Yorùbá fún àwọn àjèjì gẹ́gẹ́ bí èdè àkọ́kúntẹni. Olùkọ́ tí ó bá fẹ́ kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó sì fẹ́ ṣe àṣeyege gbọ́dọ̀ lè kọ́ èdè yìí gẹ́gẹ́ bí àkọ́kúntẹni. Èyí yàtọ̀ gédégédé sí bí a ṣe ma ń kọ́ àwọn elédè àbínibí. A rí lára àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá tí ó jẹ́ àìní ìmọ̀ tó kún tó ma ń jẹ́ kí wọ́n má a kọ́ àwọn àjòjì yìí bí ẹni pé elédè àbínibí ni wọ́n. Bí àpẹẹrẹ, a rí àwọn olùkọ́ mìíràn tí ó jẹ́ pé wọ́n ma ń bèrè kíkọ́ àwọn àjèjì pẹ̀lú kíkọ́ wọn ní ìró èdè Yorùbá, èyí ni a, b, d, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, àwọn ọ̀rọ̀ onísílébù kan, lẹ́yìn èyí wọ́n lè tẹ̀ síwájú pẹ̀lú ọ̀rọ̀ onísílẹ́bù méjì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àpẹẹrẹ, àwọn olùkọ́ yìí yóò kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí ni ba, be, be, bi, bo, bu, Àwa lérò pé olùkọ́ kọ̀ gbọdọ̀ sọ pé òun fẹ́ kọ́ nípa ọ̀rọ̀-ìṣe, tàbí ọ̀rọ̀-orúkọ, tàbí ọ̀rọ̀-arópọ̀ orúkọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ bí a ṣe sọ ọ́ lókè yìí. Eléyìí kọ̀ yẹ kí ó rí bẹ́ẹ̀ rárá.

Ní kíkọ́ èdè àkọ́kúntẹni, ó ní àwọn òté kan tí a gbọ́dọ̀ tẹ̀lé, tí gbogbo àwọn ẹni tí ó ń kọ́ èdè yìí sì ma ń tẹ̀lé jákèjádò àgbáyé. Àwọn náà ni ìmọ̀óṣe nínú èdè mẹ́rin tí a ní wọ̀nyí. Ìmọ̀óṣe nínú ìfetísílẹ̀, ìmọ̀óṣe nínú sísọ, ìmọ̀óṣe nínú ìwé kíkọ, àti ìmọ̀óṣe nínú ìwé kíkà. Nínú ìmọ̀óṣe nínú ìfesísílẹ̀, olùkọ́ gbọ́dọ̀ lè kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ láti lè mọ̀ bí a ṣe lè fi etí sílẹ̀ láti gbọ́ èdè tuntun tí akẹ́kọ̀ọ́ fẹ́ láti kọ́ kí ó lè ye yékéyéké. Ní ti ìmọ̀óṣe sísọ, lẹ́yìn tí akẹ́kọ̀ọ́ ti fi etí sílẹ̀ tán, ó gbọ́dọ̀ lè máa sọ ohun tí ó gbọ́ lẹ́nu olùkọ́ bí ó ṣe gbọ́ o kí àwọn ọ̀rọ̀ náà lè dá lẹ́nu rẹ̀ ṣáká. Èyí ni yóò jẹ́ kí sísọ rẹ̀ dán mọ́rán nígbà tí ó bá yá. Lẹ́yìn èyí ni olùkọ́ yóò wá kó ìmọ̀óṣe kíko, tí akẹ́kọ̀ọ́ yóò fi lè kọ gbogbo ohun tí ń sọ lẹ́nu sílẹ̀. Ní parípari rẹ̀, olùkọ́ yóò wá kó akẹ́kọ̀ọ́ bí ó ṣe lè ka ìwè tí ó ti ń gbìyànjú láti kọ́.

Àwọn ìmọ̀óṣe mẹ́rẹ̀ẹ̀rin yìí jẹ́ kòṣéémànì fún kíkọ́ èdè àkọ́kúntẹni. Nítorí pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti ní ìmọ̀ lórí èdè kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, kò ṣe-é-ṣe fún olùkọ́ mọ́ láti sọ pé òun fẹ́ má kọ́ ọmọ gẹ́gẹ́ bí elédè àbínibí. Àwọn èròńgbà kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù àti ìlànà tí a ti fi lélẹ̀ fún kíkọ́ àwọn àjòjì tí ó fẹ́ kọ́ èdè àkọ́kúntẹni yóò ran olùkọ́ lọ́wọ́ láti mọ ohun tí ó yẹ kí ó kọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò í tì dán mọ́rán, àjọ National African Language Resource Center ti yunifásítì ti Indiana ní ìlú Amẹ́ríkà ti ń ṣe agbátẹrù àti gbé kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù àti ìlànà kan gbọ̀ọ́gí jáde fún

gbogbo àwọn tí ó ń kọ́ èdè Yorùbá. Àǹfààní gidi tí ó wà nídìí síṣe àmúlò ìlànà yìí ni pé irú gírámà kan náà ni gbogbo olùkọ́ èdè Yorùbá yóò máa kọ́ jákè-jádò gbogbo ibi tí àwọn ọmọ ti ń kọ́ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí àkọ́kúntẹni, èyí yóò si jẹ́ kí wọ́n lè fenukò lórí àwọn nǹkan tí ì bá dojúrú nínú kíkọ́ gírámà èdè yìí.

A kò lè ya kíkọ́ àṣà nínú èdè kúrò ninu kíkọ́ gírámà èdè. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, kò bójúmu rárá tí olùkọ́ bá kàn wọ kíláàsì kí ó sì má a kọ́ àwọn àjòjì ní ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀ ìṣe, ẹ̀yán, oríṣiríṣi gbólóhùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gẹ́gẹ́ bí ìrírí tiwa, yóò ṣòro fún akẹ́kọ̀ọ́ láti rójútùú ohun tí ó fẹ́ kọ́ àti ohun tí ó fẹ́ mọ̀. Ohun tí àwọn onímọ̀ èdè àkọ́kúntẹni fi yé wa ni pé ó rọrùn láti kọ́ àjèjì ní èdè tí ó fẹ́ mọ̀ tí a bá kọ́ ọ nínú àṣà èdè náà. A rí àṣà àti gírámà gẹ́gẹ́ bíi ẹran àti eegun ni, a sì mọ̀ pé a kò lè dé ọ̀dọ̀ eegun tí a kò bá kọ́kọ́ tú ẹran tí ó bò ó palẹ̀. Ìwádìí fi hàn pé ohun tí wọ́n bá kọ́ irú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ báyìí ma ń wọ̀ wọ́n lórí ju ìgbà tí wọ́n bá kàn ń kọ́ wọn ní ba, ba, be, bi, bo, bọ́, bu, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn tí ó nífẹ̀ẹ́ sí kíkọ́ Yorùbá ni ó jẹ́ pé orúkọ Yorùbá ni wọ́n kọ́kọ́ má ń jẹ́. A lè lo àwọn orúkọ Yorùbá láti kọ́ gírámà èdè.

1. Bí àpẹẹrẹ:
   a. Adébọ́lá *the crown meets with wealth* ló di
   **Adé** bá **ọlá: Adé** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ, **bá** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ ìṣe àti **ọlá** tí ó jẹ́ àbọ̀

   b. Adébọ́rọ̀ *the crown meets wealth ló di*
   **Adé bá ọrọ̀: Adé** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ **bá** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ ìṣe àti **ọrọ̀** tí ó jẹ́ àbọ̀

   c. Adébóyè; *the crown meets the title*
   **Adé** bá **oyè: Adé** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ **bá** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ ìṣe àti **oyè** tí ó jẹ́ àbọ̀

   d. Ìbíkúnlé; *birth(children) fill the house*
   **Ìbí kún ilé**: Ìbí tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ **kún** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ ìṣe àti **ilé** tí ó jẹ́ àbọ̀

   e. Ìbílọlá; *birth is wealth*
   **Ìbí** ni **ọlá: Ìbí** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ **ni** tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ ìṣe àti **ọlá** tí ó jẹ́ àbọ̀

A lè lo áwon gbólóhùn alábọ́dé òkè yìí láti kọ́ ìṣọ̀rí ọ̀rọ̀ àti oríṣiríṣi ẹ̀yà gbólóhùn inú èdè Yorùbá. Bákan náà, a tún lè lo oríṣiríṣi ìtàn àròsọ àti akọ́nilọ́gbọ́n àti onírúurú orin láti kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní oríṣiríṣi ẹ̀yà gbólóhùn, ìṣèdá ọ̀rọ̀, onírúurú àpólà nínú gírámà èdè Yorùbá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bákan náà, yóò tún rọrùn láti kọ́ bí sílébù èdè ṣe rí pẹ̀lú àwọn orúkọ Yorùbá yìí. Yàtọ̀ sí kíkọ́ ìhun orúkọ Yorùbá, olùkọ́ tún lè fi òkò kan pa ẹyẹ méjì láti kọ́ ìró ohùn àti ìṣesí wọn nínú èdè náà.

1. A tún lè lo orin láti kọ́ òǹkà Yorùbá. Lára àwọn orin tí a lè lò ni:
   **Ení** bí ení,
   Èjì bí èjì,
   **Ẹ̀ta** ǹ tagbá

Ẹ̀rin wọ̀rọ̀kọ̀
Àrún ǹ dógó,
Ẹ̀fà ti èlè
Méje n biro,
Ẹ̀jọ ni bàtá
Mo jálákẹ̀sán
Gbangba lẹ̀wá.

Tí a bá wo àwọn ìwè kíkọ́ ọmọ tí àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá fún àjọ̀jì kọ àti pàápàá èyí tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Schleicher kọ, àwọn bí i *Jẹ́ K'á Sọ Yorùbá* àti *Jẹ́ K'á KaYorùbá*, a ó ri pé wọ́n tẹ̀lé irú ìlànà tí à ń sọ yìí. Báwo ni wọ́n ṣe ṣe? Ohun tí wọ́n ṣe ni pé wọ́n ń kọ́ àwọn ọmọ yìí ni oríṣiríṣi àṣà nípa gbígbe wọn lóri àwọn ìmọ̀ọ́ṣe mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí a mẹ́nubà lókè, nípa síṣe báyìí, oríṣiríṣi àwọn ohun tí ó yẹ kí á kọ́ nínu gírámà èdè Yorùbá ni ó ma ń yọjú. E jẹ́ kí á mú ìmọ̀ọ́ṣe kíkà gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ.

Tí a bá gbé àyọkà kan jáde lórí ìkíni tí ó tó bí ojú-ìwé mẹ́ta, lẹ́yìn tí àkẹ́kọ̀ọ́ bá ti ní ìmọ̀ kíkún lóri ìkíni ní èdè Yorùbá tán, olùkọ́ yóò tún má wa tọ́ka sí àwọn ohun tí ó jẹ mọ́ gírámà nínú àyọkà náà. Nínu rẹ̀, olùkọ́ lè rí ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-ìṣe, ẹ̀yán, ọ̀rọ̀-àpèjúwe, oríṣiríṣi gbólóhùn tí ó bá jẹ yọ nínú àyọkà náà. Irú kíkọ́ báyìí ni yóò jẹ́ kí ohun tí akẹ́kọ̀ọ́ kà wọ̀ ọ́ létí ti yóò si fi jẹ́ kí ó ní ìmọ̀ kíkún nínú èdè Yorùbá.

## Àgbálọgbábọ̀.

Nínú iṣẹ́ yìí, a ti wo bí a ṣe lè kọ́ àwọn àjọ̀jì ní èdè Yorùbá, a sì wo àwọn ohun tí ó yẹ kí á kọ́ àti oríṣiríṣi ọgbọ́n ìkọ́ni tí ó yẹ kí á mú lò tí yóò fi jẹ́ kí isẹ́ wa kẹ́sẹ járí. Nínú iṣẹ́ yìí náà ni a ti sọ nípa oríṣiríṣi ohun tí àwọn àjọ̀jì rí lọ́bẹ̀ tí wọ́n fi waro ọwọ́ nípa kíkọ́ èdè Yorùbá. A gbọ́dọ̀ jẹ́ kí á mọ̀ pé kì í ṣe pé a sọ pé gbogbo ohun tí a sọ lábẹ́ ìsọ̀rí yìí nìkan ni ó mọ. Ọ̀pọ̀ ìdí ni ó tún lè wà tí a kò lè mẹ́nubà tí àwọn àjọ̀jì fi lè kọ́ èdè tí kì í ṣe tiwọn. Lẹ́yìn èyi ni a wá ṣàlàyé kíkún lórí oríṣiríṣi ọgbọ́n ìkọ́ni tí olùkọ́ gbọ́dọ̀ mú lò tí ó bá ń kọ́ àwọn àjọ̀jì ní èdè Yorùbá tí yóò fi jẹ́ kí isẹ́ rẹ̀ lójútùú.

A tún gbọ́dọ̀ jẹ́ kí a mọ̀ pé àwọn ohun kan tí ó tún ṣe kókó ní kíkọ́ gírámá lẹ́yìn àwọn ohun tí a mẹ́nubà lókè yìí wà. Kíkọ́ nipa gírámà èdè dálé ọ̀nà ẹ̀kọ́ nípa àwọn òfin tí ó de gírámà tí yóò mu kí ó rọrùn fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti lè wẹ̀ kí wọ́n yán kànkàn nipa lílè so èrò ọkàn wọn, kí ohun tí wón bá ń bá wọn sọ lè yé wọn yékéyéké, kí wọ́n sì lè tú tìfuntẹ̀dọ̀ àwọn ìwé tí wọ́n bá kà. Èròngbà kíkọ́ èdè ni pé, nígbà tí akẹ́kọ̀ọ́ bá fi máa kẹ́kọ̀ọ́ gboyè ní ilé ẹ̀kọ́ rẹ̀, ó gbọ́dọ̀ lè ti mọ gbogbo tìfuntẹ̀dọ̀ èdè náà bíi, gbogbo gírámà èdè, àkọtọ́ àti àwọn ọ̀rọ̀ tí ó jẹyọ nínú èdè náà. Lákòótán, tí olùkọ́ bá lè kọ́ gírámà èdè ní àkọ́dunjú, tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà sí mọ̀ọ́ ní àmọ̀dájú, yóò jẹ́ kí wọ́n lè ní ìmọ̀ kíkún bí èdè

àbínibí yìí ṣe ń ṣiṣẹ́. A gbọ́dọ̀ jẹ́ kí a mọ̀ pé ṣókí, bí ọbẹ̀ oge ni a fi iṣẹ́ yìí ṣe. A mọ̀ pé iṣẹ́ sì pọ̀ tí ó yẹ kí á mẹ́nubà, ṣùgbọ́n ohun ti a ò kàn sọ ni pé ó tán lẹ́nu, ó kù níkùn.

## Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí


Adẹ́níyì, Harrison. "Yorùbá Studies in the United States" in Tóyìn Fálolá, and Ann Genova (eds.) in *Yorùbá Creativity: Fiction, Language and Songs*. New Jersey: African World Press. 2005.

Adẹ́níyì, Harrison. R. "Kíkọ́ Fónẹ́tíìkì àti Fonólójì Yorùbá ní ilé ẹ̀kọ́ sẹ́kóńdírì olódún mẹ́ta àkókó: Àkóónú àti ogbón ìkóni" nínú *Láǹgbáàṣà: Jónà ìmọ̀ akadá ní èdè Yorùbá*. Lagos. University of Lagos. 2000.

Adéníyì, Harrison. R. Ìlò-èdè *àti èdá-èdè Yorùbá: Apá kìíní*. Lagos. Harade and Associates. 2000

Àrásanyín, Frank O, Antonia Y. Folárìn-Schleicher, and R. Ṣekóoní. "A Goal-Driven Curriculum" Unpublished manuscript. Washington, DC. National Foreign Language Center, John Hopkins University. 1996.

Bokamba, Eyamba. G. *African Language Program Development and Administration: A Historical and Guidelines for Future Programs*. Madison.WI: National African Language Resource Center. 2002.

Dougherty, J. "A Hisory of Federal PolicyConcerning College or University-Baṣed Foreign Language and Area Studies Centers, 1941–1980 [Army Specialized Program National Defense Education Act]" PhD. Disc. University of Maryland at College Park. 1993.

Folárin-Schleicher, F and Moshi, L. *The Pedagogy of African Languages: An Emerging Field*. Columbus. The National East Asian Languages Resource Center. The Ohio State University. 2000

Hare, Donna.L. "Sputnik and United States K–12 Science Education" Unpublished PhD. Dissertation University of Nebraska, at Lincoln. 1999.

Kurtt, Sharon, B. "A Study of an Agenda-Setting Model as Applied to the Passage of the National Defenṣe Education Act of 1958" Unpublished Dissertation, University of Iowa at Iowa City. 1999.

Lambert, Robert. *Beyond Growth: The Next Stage in Language and Area Studies*. Washington DC. Asscation of American Universities. 1984.

Lambert, Robert. "Problems and Procesṣes in US. Foreign Language Planning" in *Foreign Language Planning: An Agenda for Change. Special Issue of the Annals of the American Association of Political and Social Science, Vol.532* edited by R.D Lambert, 123–37. Thousand Oaks, CA: Publication Sage. 1994a

Moshi, Lioba. "The Teaching of African Languages" *Penn Language News* (spring): 1–6. NERDC. 1981.

Ruther, Nancy. L. *The Roles of Federal Programs in Internalizing the United States Higher Education System from 1958–1988.* PhD Diss. University of Massachuşetts at Amherest. 1994.

Swenson, S.B. "International Education and the National Interests" The National Defense Education Act of 1958, The International Education Act of 1966, and the National Security Act of 1991" PhD Thesis: University of Oregon, Eugene, Oregon. 1999.